السنّة النبوية وعلومها
www.sunnah.global

# “Dájúdájú àwọn onideede maa wa lori minbari latara imọlẹ ni ọdọ Ọlọhun, ni ọwọ ọtun Ajọkẹ-aye ti O lágbára ti O gbọnngbọn, ọ̀tún si ni ọwọ Rẹ̀ méjèèjì

Lati ọdọ Abdullahi ọmọ Amru - ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pé: “Dájúdájú àwọn onideede maa wa lori minbari latara imọlẹ ni ọdọ Ọlọhun, ni ọwọ ọtun Ajọkẹ-aye ti O lágbára ti O gbọnngbọn, ọ̀tún si ni ọwọ Rẹ̀ méjèèjì, àwọn ti wọn n ṣe deede nibi ìdájọ́ wọn, ati lọ́dọ̀ àwọn ará ilé wọn, ati nibi ohun ti n bẹ lábẹ́ àṣẹ wọn”.

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe àwọn ti wọn n dajọ pẹ̀lú deede ati òdodo láàrin àwọn èèyàn ti wọn n bẹ lábẹ́ àṣẹ wọn ati idajọ wọn, ati ara ile wọn, wọ́n maa jókòó lori aga ti o ga ti wọn da latara imọlẹ, láti ṣe apọnle wọn ni ọjọ́ igbende. Ọwọ́ ọ̀tún Ọlọhun ni àwọn minbari yii maa wà, ọ̀tún si ni ọwọ Rẹ méjèèjì.

https://sunnah.global/hadeeth/yo/show/4935

النجاة الخيرية
ALNAJAT CHARITY
لجنة الدعوة الإلكترونية
EDC E-Da'wah Committee